# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,597 WEDNESDAY DECEMBER 29, 1965 (2D)


28 JAN 1966 LIBRARY PUBLICATIONS EXCHANGE

## Oko Oju Omi Kan D'Ojude Sinu Odo Osa

EKO:– Jinnijinni dabo gbogbo awon enia ti nwon wa nitosi nigbati nwon ri Okunrin apeja kan, Ogbeni Alaso ti o nda eja ninu odo Osa niwaju ile ise awon Oyinbo onisowo ti nwon npe ni "John Holt" ni Marina ti Okunrin na sinu omi nigbati o fe fi iwo re gbe eja kan jade ninu omi ni deede agogo ... ale ana ojo Aje ti ise ojo ketadinlogbon osu yi

Irohin awon Olopa oko Oju Omi fi ye wa wipe, ise apeja ni Okunrin na nse, o si ti wa ni oju omi lati ale ana ti ko ri eja kankan pa. sugbon nigbati o di owuro ojo na ni o ba pinnu wipe nigbati on ko ri eja kankan pa ki on ma a lo si ile

Nibiti o ti nro ero yi lowo ni o ba ju awon re sinu odo ni eti Ebute na wipe boya on yio ri eja pa nibe, sugbon bi o ti ju awon na sinu odo ti o si fe fan jade ni awon na ko ba se fa mo, bi o si ti dide wipe ki on sunmo eti oko na ki on le ba ri aye lati fa eja na jade ni ese re ba seesi tase ti oko re si dojude sinu omi osa.

Gbogbo awon enia ti nwon wa nitosi ibe ni nwon sare wa lati gba Okunrin na sile, sugbon bi nwon ti se to nwon ko ri oku ati aye Okunrin na titi di igbati a fi nkowe yi ni ale ana

# ROGBODIYAN MIRAN BESILE NI IWO ORUN !

## Nwon Dana Sun ile Mejo Ni Ikenne

IBADAN,– Ninu irohin to tun de ile ise wa lati Ibadan Ipinle Iwo Orun Naijiria ni a ti gbo wipe rogbodiyan miran ti tun nsele laarin awon omo egbe oselu lori eto abayori idibo si Ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria eyiti awon se idibo re ni ojo kokanla osu kewa odun yi.

... rogbodiyan to be ... odun keresimesi ti nwon se koja lo yi ni awon enia kan ti dana sun ile awon Olori egbe oselu mejo kan ni ilu Ikenne Ijebu Remo eyiti awon enia na tun ba ile medogun miran je.

Ninu irohin ti ... gbo ... ni awon enia kan ti ... ko mo won lo kolu ile ise ... awon gba ... ilu na ... awon ... wipe gbogbo ilu na lo ... oko kan bi ... awon enia ... to beresi dana sun awon ile na ti awon si tun ba awon ile miran je eyiti o je wipe awon enia na ba awon ile na je koja eyiti ... tele se ...

Irohin na tun fi ye wa pe ... to be ... ni ... awon Egungun kan ti beresi kolu awon enia na eyiti o je wipe awon Egungun na pelu awon omo egbe oselu na si beresi kolu ara won ti awon si nsa ara won ladu gegebi ... awon nsa eran ... Irohin na tun fi ye wa pe awon ti gbe awon enia to fi ara gbogbe lo si ile iwosan ti ilu Ijebu ... lati lo se itoju won nibe.

Oniwe irohin wa to wa ni ilu Ikenne nibi isele na ti ye wa pe lesekese ni awon Olopa yara de si ilu Ikenne lati pa ina naa to njo laarin awon ile na eyiti o fi je pe gbogbo wahala ti awon Olopa na se si ja si asan.

Ko si ... pupo na ni awon Olopa lo mu awon ... egbe oselu merin kan ... ile won eyiti o je pe, awon Olopa si se iwadi ... to ... na owo iwon. Sugbon awon

Olopa na si da nwon olori egbe oselu merin na sile eyiti nwon fi gba iduro awon olori egbe oselu na.

Ninu irohin ti o de owo wa lati ilu Ijebu Igbo tun fi ye wa pe awon enia kan tun lo kolu Okunrin kan tiso ... ni ... ile ise ibi ti nwon gbin ... si eyiti ise ti Ijoba Ipinle Iwo Orun ni Apo ... bi Ijebu Igbo Ogbeni Yatha ... Oye ... ko ... awon enia ... si ... da eyiti o je wipe ... re si wa ni ... ile iwosan ti ilu Ijebu ode bayi.

Ni ilu Ile Ife ni irohin ti fi ye wa pe Ogbeni Idowu Bamishe ti o je Onisowo ... eyiti awon enia na kolu ni oju ona yekere ti won gbe lo si ile iwosan ilu na lose to koja yi ni a wipe o ti ku ninu ile iwosan na bayi.

Irohin fi ye wa pe Ogbeni Idowu Bamise ... si ilu Ilesha ... ati awon enia kan ti won je omo egbe oselu lo kolu ti awon enia na tun dana sun moto ti Ogbeni Bamishe gbe lo si Ilesha.

A gbo wipe awon Olopa ti mu enia medogun bayi lori awon koko meji ... ti awon enia kan dana sun eyi ti gbogbo koko to wa ninu awon ile ti nwon ko awon koko na si jona patapata.

Bakanna ni awon enia na tun dana sun moto ayokele kan ti o wa l'ebaile ibiti nwon nko awon koko na si Irohin na tun se alaiye pe gbogbo moto na lo jona raurau eyiti o je pe ko si le se tun se bayi.

Awon okunrin meji kan ti nwon nso ile ibiti nwon nko awon koko na si ni irohin fi ye wa pe awon ti gbe awon enia na lo si ile iwosan ti ilu Ile Ife lori ibiti awon ti fi ara gbogbe ada eyiti awon enia na ti sa won a si gbo wipe ni ... emi awon Asode meji na wa ni isisiyi.

Irohin lati owo awon Olopa to wa ni Ile-Ife tun fi ye wa pe awon ko ti mo oruko awon Asode meji ti awon enia na lo kolu bayi.

Ninu irohin to de owo wa lati owo oni we irohin wa ni ilu Ota Aiyegbaju fi ye wa pe ile meta ni awon enia kan dana sun ni ojo aisun odun Keresimesi eyiti o je wipe awon dukia to segbe sinu ina to jo awon ile na si to egbe gbeta ponun (£5,000)

# Layeni Se Are Itan Awolowo

Irohin ko to alojuba ni are alarinrin eyiti Ogbeni Layeni se ni Gbogan Glover ni ale ijeta ti ise ojo Aje ojo ketadinlogbon osu yi



Ki o to di wipe are na bere ni gbogbo Kansilo Ile Igbimo Asofin Ijoba Ibile Eko ni nwon ti de si ibi are na ni akan bi agogo mejo ale

Nigbati o si di deede agogo mejo abo ni are na bere nigbati are na bere, nse ni gbogbo awon enia nyombo Ogbeni Layeni ti nwon si nkan saara sii.

Ogbeni Layeni bere are na, lati Igbati Oloye Obafemi Awolowo wa ni omode titi ti Igbati omo re Segun Awolowo fi di Ologbe.

Nigbati are na de ibiti nwon ti lo tu Ofo Iku Segun Awolowo fun Baba re ninu Ogba ewon, nse ni gbogbo awon ero ti nwon wa si ibi are na busekun, ti nwon si nfi aso nu oju won.

Onirohin wa ti o lo si bi are na fi ye wa wipe, awon enia ti nwon lo woran are na le ni Oke meji 40,000,000 enia.

Are na si pari ni deede agogo mejila abo Oru Ojo na.

Aworan Oke iwe yi niti awon omo Layeni ti nwon nse are na.

# ADEHUN AJỌṢEPỌ LARIN AWON ORILẸ — EDE MEJI

Ninu awọn ohun miran ti a tun gbọ wipe awọn enia na tun sọrọ le lori ni awọn ohunti nṣelẹ ni Orilẹ ede Vietham ati ilẹ Rodesia. Awọn enia na tun mu ẹnu ba ọrọ awọn Ijọba Orilẹ ede Alagbara aiye ti nwọn nda awọn ohun ẹṣẹ wo ni oju ọrun tabi ni isalẹ ilẹ nwon tun sọro lori bi awon ti se le fi opin si gbogbo rẹ ti alafia ati iṣokan yio ṣe wo Orilẹ ede gbogbo yika aiye.



**Olola Josip Broz-Tito ati Iyawo Rẹ**
OLORI IJỌBA YUGOSLAVIA

Lẹhin irade won, awọn enia ẹgbẹ mejeji so fun awon Oniwe Irohin wipe ajọṣepọ ti o ti wa larin awon mejeji yio tubọ fi ẹsẹ mulẹ dahindahin ju ti atẹhinwa lo.

Ajọṣepọ iṣẹ aje eyiti o wa larin ilẹ Naijiria ati Yugoslavia jẹ eyiti o fi ẹsẹ mulẹ daradara ti ko si le yẹ Bi o ti wulẹ kori awọn Ijọba mejeji si tun nwa ọna nisisiyi bi wọn yio ṣe ma ṣe alekun iṣẹ ọwọ ati owo larin ara wọn.

Nitori idi eyi ni awọn Ijọba mejeji ṣe ran aṣoju si ara wọn nipa bi ajọṣepọ na ko ṣe ni le yẹ larin ara wọn ti ede awọn mejeji yio si wa ni ọkan soso.

Ninu ọdun 1961 titi di isisiyi Ijọba Orilẹ ede mejeji ti ran awọn Asoju si ara wọn ni aiko aiye igba ti nwọn si nwa ọna lati maa lepa bi okan na yio ti se tun maa lọ siwaju larin ara wọn.

Nitori idi eyi ni awon Ijoba mejeji se ran aṣoju si ara won nipa bi ajọṣepọ na ko se ni le yẹ larin ara

wọn ti ede awọn mejeji yio si wa ni ọkansoso.

Ninu ọdun 1961 titi di Isisiyi Ijọba Orilẹ ede mejeji ti ran awọn Asoju si ara wọn ni aiko aiye igba ti nwọn si nwa ọna lati maa lepa bi okan na yio ti se tun maa lọ siwaju larin ara wọn.

Awọn enia kini ti nwọn kọkọ lọ si Orilẹ ede ilẹ Y u g o s l a v i a ni Oloye Samuel Ladoke Akintọla, ẹniti ise Alakoso Ijọba ipinlẹ Iwọ orun nwọn lọ si orile ede na ninu ọdun 1961 lati lọ si ibẹwo Orilẹ ede na ki nwọn si to tun pada wa si ile.

Sugbọn nigbati o tun di osu kẹwa ọdun 1961, ni Apapọ Ijọba Naijiria tun ran awọn ikọ kan ti nwọn tun lọ si orilẹ ede ilẹ Yugoslavia lati tun lọ se abẹwo si ilẹ ede na ki nwọn si lọ wo awọn ti awọn jẹ Alakoso Ijọba orilẹ ede na

Ẹniti ijọba ran lọ nigbana ni Oloye Festus Samuel Okotiẹ Ẹbọh ẹniti ise Minisita Alamojuto eto inawo fun Apapọ Ijọba Naijiria pẹlu awọn enia kan ti wọn tun lọ pẹlu rẹ ni gba a.

Bakanna ẹ wẹ, nigbati o tun di osu kẹfa ọdun 1964, ni Apapọ Ijọba Naijiria tun ran awọn enia miran lati tun lọ si Orilẹ ede ilẹ Yugoslavia lati tun lọ wo orilẹ ede na, enia ti nwọn si ran lọ nigbana ni Alhaji Zana Bukar Dipcharima ẹniti iṣe Minista Alamojuto eto owo fun Apapọ Ijọba Naijiria.

Gbogbo awọn enia ti Ijọba ran lọ si Orilẹ ede Yugoslavia nigbana ni awọn ba Ijọba won se adehun nipa iṣẹ owo ati iṣẹ aje bi gbogbo nkan na yio se maa lọ siwaju ninu awon Orilẹ ede mejeji nipa ajosepo won ninu gbogbo awon ohunti nwọn yio maa se.

Nigbati o si di inu ọdun 1963, ni Ijọba Orilẹ ilẹ Yugoslavia a tun ran awọn enia ti won lati wa wo Orilẹ ede ilẹ Naijiria, ki awon na si mọ bi gbogbo nkan ti ṣe ri ninu ilu na ki awon si tun mọ awọn ohunti Ijọba Yugoslavia yio ma ra lati ilẹ Naijiria ati ohunti awon yio maa kowa si ilẹ Naijiria ati ohunti awon yio maa ko wa si ilẹ Naijiria fun tita larin ara awon.

Ẹniti o ṣe Aṣiwaju awọn enia ti Ijọba Yugoslavia ran wa nigbana ni Ọgbẹni Ijubo Mijatovo, ẹniti iṣe akowe ise owo fun Ijọba orilẹ ede Yugoslavia.

Nigbati awọn enia na de ilẹ Naijiria, awọn iroro pẹlu awọn alaṣẹ eto Apapọ Ijọba Naijiria fun ọna ti awọn Ijọba mejeji na lo ma gba ti gbogbo nkan yio ti ṣe ma lọ siwaju larin ara wọn ti iṣe owo ati iṣẹ Aje na yio ṣe maa lọ deede.

Lẹhinti awọn enia mejeji ti jọ ṣe asaro lori gbogbo awọn ohunti nwọn fẹ se tan ni awọn enia mejeji na wa fi ọwọ si iwe adehun larin arawọn ohunti nwọn fẹ ma ta fun ara wọn ati iru irànlọwọ ti Ijọba.

Ninu ọrọ ti awon enia na so ni ojo na, awon Aṣoju Ijoba Orilẹ ede ilẹ Yugoslavia so nigbana wipe awon yio maa ko awon omo ilẹ Naijiria ni ona iṣẹ owo, eko ijinilẹ, ise agbe, ati orisirisi awon ise miran ti o ba tun wulo fun awon omo Naijiria

Awon Aṣoju na so ni gbana wipe, ni afikun, awon yio tun fun Orilẹ ede Naijiria ni owo, lati ma a fi tun awon ibiti o ba bajẹ se tabi ti nwọn ba nfe atunse ninu ilu won

Awọn enia na wa sọ nigbana wipe awọn yio ṣe iranlọwọ ẹdẹgbẹta okẹ pọnun (3, 600, 000) fun Naijiria ki awon maa fi ṣe ise fun Idagbasoke ilu ati gbogbo awon ibiti o ba nfẹ atunse.

Lati igbana ni awon Orilẹ ede Yugoslavia ti bẹrẹ si maa ba ilẹ Naijiria ra ọja ti awọn ọja ti Ijoba na nba ilẹ Naijiria ra loni ni koko, Rọba, kọfi, owu, igi-gẹdu, ekuro, ẹpa ati awon nkan wẹwẹ miran.

Irohin ti a ti gba ni ibẹrẹ ọsẹ yi lati ile iṣẹ Asoju Ijọba Orilẹ ede Yugoslavia ni Naijiria fi ye wa wipe lati inu ọdun 1964 ti adehun yi ti wa larin awon Ijoba mejeji Ijoba ilẹ Yugoslavia ti ra ọja ti ọkẹ mẹtadinlọgọta pọnun (£1, 220, 000) ni-sisiyi.

WO OJU EWE KARUN

# AWỌN ỌMỌ IṢEYIN ṢE BẸBẸ L'EKO

EKO:- Gbogbo ile lo kunṣoṣo ti ẹse ko si gba ero fun ogunlọgọ ọkẹ aimoye awọn ọmọ ibile ilu Iṣeyin ti nwọn wa ni ilu Eko, Ebute-Metta, Yaba, Surulere, Mushin ati Shomolu nṣe ayẹyẹ ifi ẹgbẹ ọmọ Ibilẹ ti ilu Iṣeyin ẹka Eko lelẹ ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi ninu Gbọgan ile ẹkọ ti Hamadiya, Idi Iẹgbata, Eko.

Ki awọn ọmọ ilu Ibilẹ Iṣeyin to bẹrẹ ipade fifi lati ẹgbẹ titun na lele ni ilu Eko ni awọn enia jankanjankan, Olori ẹgbẹ Oṣelu Minista ati awọn Ọga agba ninu ile iṣẹ Ijọba apapọ Naijiria ati Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria l'okunrin ati l'obinrin ti pesẹ sibi ayeye ipade ọjọ na.

Nigbati ipade na bẹrẹ ni awọn ọmọ ibile Iṣeyin yan Ọgbẹni S. A. Yerokun gẹgẹ eniti yio ṣe alaga ayeye ipade ọjọ na eyiti Akọwe agba ẹgbẹ na ṣe ikede rẹ.

Lẹhin na ni Ọlọla S. A. Yerokun Minista kekere fun Apapọ Ijọba Naijiria ṣe alaye nipa ohunti o ṣe pataki ti awọn ọmọ Ibilẹ ilu Iṣeyin titori rẹ pesẹ ni ọjọ na ati pe o kesi ninu awọn ọmọ ilu na ti o le sọ nipa itan ẹgbẹ ọmọ Ibilẹ ilu Iṣeyin eyiti awọn ọmọ ilu na ni ilu Ibadan ati ni ilu Iṣẹ... ti da silẹ ati ero ọkan awọn ẹgbẹ titun na.

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Alimi Aderoju dide ti o ṣe alaye kukuru fun awọn ọmọ ilu na lori iṣẹ ribiribi ti o wa lọkan awọn ọmọ ẹgbẹ Ibilẹ ilu Iṣeyin lati se ati pe o tun ṣe alaye lori anfani yan ti awọn ọmọ ilu na to wa ni Ibadan ati nile ṣe ni pa dida ẹgbẹ na silẹ ninu ọdun keji ṣẹhin.

Nigbati Ọgbẹni Alimi Aderoju pari ọrọ rẹ tan ni nwọn ọmọ Ibilẹ ilu Iṣeyin ti ẹka Eko pinnu lati yan awọn Oloye titun fun idasilẹ ẹgbẹ titun na eyiti nwon ẹka ẹgbẹ na wọ mu ilu Eko ni ọjọ na.

Eleyi ni awọn Oloye titun ti awọn ẹgbẹ na yan fun eto akoso ẹgbẹ titun na. Awọn ẹgbẹ na yan Ọgbẹni Ọlabisi Ajala eniti o ṣe eto irinajo kakiri agbaiye ti o si ti pari iṣẹ na ati pe o si jẹ ọkan pataki ninu awọn Oniwe Irohin ni ile Oniliria gẹgẹbi Olori ẹgbẹ na, Ọgbẹni Kọlade Igbakeji Olori ẹgbẹ, Ọgbẹni Badru Rabiu, Akọwe agba, Ogundiran Igbakeji Akọwe, Omidan Bintu Sule Akọwe eto owo, Alimi Aderoju Akapo, Fọla Aderoju, Olusiro owo, B. Owokoniran Akọwe eto irohin, ati R. O. Ajala gẹgẹbi Akọwe eto Alafia ẹgbẹ

Ninu ọrọ Olori ẹgbẹ na titun ni Ọgbẹni Ọlabisi Ajala ti dupẹ gidigidi lọwọ awọn ọmọ ibile Iṣeyin gegebi ipo ti nwọn yan si O tun rọ awọn ọmọ ilu na lati isowopo fun eto bi ilosiwaju ati idagbaso e yio ṣe wa ni-ilu na.

Ọgbẹni Ọlabisi Ajala tun ṣe alaye lori Ọna eyiti ẹgbẹ na eyiti o ṣe wipe ko fi ara mọ ẹgbẹ Oṣelu kankan ati pe o wa fun gbogbo ọmọ ilu ṣeyin lọkunrin ati lobinrin lati wa igbega ilu Iṣeyin

Siwaju si Ọgbẹni Ajala tun kesi awọn ọmọ ilu na lati ṣe eto bi ilu wọn ṣe di bi awọn ilu miran atipe ki nwọn maṣe duro de asiko ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ati apapọ Ijọba yio ṣe iranlọwọ fun bi koṣe pe ara ti ilu na yio ṣe ni awọn ohun idagbasoke gẹgẹbi ile ẹkọ nla ile Iwosan, Ile ifi iwe ranṣẹ ati ọpọlọpọ oju ọna eyiti awọn ọmọ Ilu na yio fi ọwọ wọn ṣe nipa eto isowopọ

Ni ipari ọrọ rẹ, Ọgbẹni Ajala tun rọ awọn ọmọ ibilẹ ilu Iṣeyin ṣe ki nwọn gbi nyanju eto bi alafia yio ṣe wa larin awọn ọmọ ilu ati pe ki a maṣe si iyasọtọ larin awọn ọmọ ilu na,

Lẹhin na ni Akọwe agba ẹgbẹ na Ọgbẹni Rabiu tun ṣe alaye lori ọna orisirisi ti ẹgbẹ na fẹ fi tun ilu wọn ṣe tabi wa ilọsiwaju si ilu wọn,

Nigbati Ọgbẹni Rabiu pari ọrọ rẹ ni Ọgbẹni Okediran Igbakeji Olori ẹgbẹ Ibilẹ Iṣeyin ti ẹka Ibadan tun ba awọn ọmọ ẹgbẹ ti tun na sọrọ lori eto ti ẹgbẹ na ti nṣe bayi lori idagbasoke ilu Iṣeyin Ọgbẹni Okediran tun sọrọ lori ipade ti ẹgbẹ na yio ṣe ni ilu Iṣeyin ni ọjọ kẹjọ osu kini Ọdun to mbọ yi.

Ọgbẹni Okediran tun rọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na lati pesẹ si ilu Iṣeyin ni ọjọ na lati le fi ẹdun ọkan olukuluku han nibi ipade ati pe ọjọ na ni Ajọ gbogbo gbo ẹgbẹ na yio yan awọn Oloye ẹgbẹ na. O tun kesi wọn pe ki ẹnikẹni maṣe sọ ohunti o ṣe ti wọn wu nipa pe ti nwọn ko ba wa sibi ipade ọla ọjọ na.

Ninu awọn enia pataki to tun wa si ibiti awọn ọmọ Ibilẹ ilu Iṣeyin ẹka Eko ti da ẹgbẹ na silẹ ni ọjọ na lati ilu Ibadan ni Ọgbẹni Okediran Igbakeji Olori ẹgbẹ na ni Ibadan, S. Adeunle, Ọgbẹni F. Ọlọrunshọ ati T. A. Akinade.


## Ila Kini Eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
LORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ An O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tun yara pa ayun ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọ ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu ori erin mẹta ni nwọn mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu itaja kakiri orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS

AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS



## KERE O !

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA" to ṣẹṣẹ jade ?

Ha ! Kosemani ni iwe na jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan iṣẹdalẹ Yoruba. Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maṣe jẹki nwọn tohun itan ilu rẹ fun ọ

3/- pere ni. Postage 9d

Tete f'owo tirẹ ranṣẹ si:

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Ijumagbo Avenue, Lagos Nigeria
( Leti Oja Jankara )

# INA PA ENIA MẸRIN NI ỌYỌ!

ỌYỌ— Ninu irohin to tun de ile iṣe wa ni kutukutu owuro ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu yi ni a ti gbọ pe enia mẹrin ninu enia mẹrun ti nwọn si jẹ ẹbi kanna ni o padanu ẹmi wọn ninu ina nla ti o pa awọn enia na laye ninu ile wọn ni ọjọ ojo 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni abuleko kan ti nwọn npe ni Oko Lẹba Ọyọ.

Ninu awọn enia ti nwọn dana sun laye na ni Iyawo ile meji ati ọmọ wọn eyiti Iṣe Obinrin Oruko awọn enia na ti nwọn padanu ẹmi wọn na Sidi Lasisi ati ọmọ rẹ Obinrin Adiyatu Lasisi, Iyaafin Adegbenjo Lasisi ati ọmọ rẹ Obinrin Risikatu Lasisi.

Ninu irohin lati owo awọn olọpa ilu Ọyọ ni won ti ṣe alaye pe awọn enia na si sun sinu ahere won ni abuleko na eyiti awọn enia na fi sọ pe otutu ngmu awon.

Irohin awon Ọlọpa na tun fi ye wa pe awọn enia na si lo sinu Igbo lati lo ṣe igi eyiti awon enia na yio da ina ti nwon si sun lo.

Irohin na tun fi ye wa pe gẹgẹbi awọn enia ti sun lo ni ina ti nwon da silẹ si fo mọ ahere na eyiti o jẹ wipe ko si ẹniti o ji ninu awon na titi ina na fi jo ti o si jo won pa.

Lẹsẹkẹsẹ ti iṣẹlẹ ina nla na ti ṣẹlẹ si awon enia na ni nwon tete gbe won lo si ile Iwosan ti ilu Ọyọ eyiti iṣe ibuso metadinladota si abuleko Owo.

Irohin tun ye wa pe ko pe pupọ ti awon gbe awon enia na de ile Iwosan ti ilu Ọyọ ti awon enia na si ku bi nubamu ti ko si ọna ni fun wọn ti awọn Dokita ri aye lati ṣe itọju won ki nwọn to ku.

Ninu ọrọ Ọgbẹni Adeleke Lasisi ti ise ọkọ ati baba awọn enia to jona na fun Oniwe irohin wa nigba ti o fi ọrọ lo wa Ọgbẹni na lẹnu wo ni o ti ṣe alaye fun o iwe irohin wa pe, ohunti o ṣẹlẹ na dabi ala loju on.

Ọgbẹni Adeleke Lasisi tun ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe oṣe ni on sun ni iwaju ahere na ati pe on ko mọ pe ina kankan ojo titi di asiko ti awon Iyawo re meji ti ina ti jo bẹrẹsi si kigbe ninu iroranu ni o to mọ pe nkan ti ṣele.

Ọgbẹni Lasisi tun ṣe alaye pe ki awon enia to wa ni abuleko na to le ṣe iranlọwọ lati le pa ina nla na ni o ṣe alaye pe gbogbo awọn enia na lo ti padanu ẹsẹ ti gbogbo na si ti jona raurau.

Awon Ọlọpa ilu Ọyọ ti bẹrẹsi ṣe iwadi ohun ti o fa ina nla na ati pe a ko ti gbo irohin kankan lati owo awon Ọlọpa ilu Ọyọ nipa ohunti o fa ina na.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Alafia mbẹ fun o loni gbogbo ohun ti iwo ko le se ni iwo yio se Ire ni ohun ti o nro lọkan rẹ yio jẹ

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Awọn enia rere ni iwọ yio ba lo po loni awon si se iranlowo ohun ti o fẹ fun o

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Ohun kan ti o ngbe rọ lati ṣe yio lera diẹ fun ọ ṣugbọn iwọ yio ri ọgbọn fi yọ ninu rẹ

GEMINI (May 21 June 21) Sa ọna bi iwọ yio ti ṣe ri owo diẹ yá loni ki o wa lọ fi ra ọja ninu Ṣọbu dajuda ju iwọ yio ri ere jẹ

CANCER (June 22 July) Ọjọ oni yio le fun ọ diẹ ni torina ki o mọ iwọn ara rẹ ma gbagbe wipe ko nse ọjọ gbogbo ni odun

LEO (July 23 Aug 22) Oro ara rẹ le di ijọgbọn bi o ko ba sọra o si le ni alafia sọrọ gidi ṣugbon maṣe ba ẹnikan jowu papo

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Jẹki suru wa ninu ohun gbogbo ti o ba nse loni ohun ti o dara ni ki o ma ro ninu ọkan nigba gbogbo

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Maṣe gba ọrọ ti to ọrọ bi ẹni gba igba ọti bi o ba si nse ojo o iwo ko ni le lọ sibi kan bẹni ọna ire pupo lo si silẹ fun o

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Idẹra ati igbadun yio wa fun ọ loni tobẹ ti iwọ yio ṣe awọn nsẹ ti iwọ ko ri aye lati ṣe ni iwọn ọjọ meta sehin

PISCES (Feb 21-Mar 20) Nigbẹhin alafia ara yio to ọ ara rẹ yio si ya kiakia bi eyi ba si ti jẹ bẹ ma se jafara lati ma wa idagba soke ati ilọsiwaju iṣe rẹ

ARIES (Mar 21 April 20) Sọra nipa egbogi lilo ki o ma ba da ọ laini ṣugbon bi o ba lo sọ ara rẹ ti o si ṣe ara giri iwọ yio ni ilọsiwaju ere yio ran ọ lowọ jojọ

TAURUS (April 21 May 20) Gbogbo ọre rẹ ni yio tẹ ọ lọwọ ti ohunti o nfẹ yio jẹ tire pẹlu ire mbẹ pupọ fun ọ bi o lọ si ode tabi ti o nrin irin ajo


# Kere o Kere o!
## Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanun Egbogi ni LEOPILLS a wa na nlọ ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na ngwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ojọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ soya tabi pe ile i fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbọnsẹ deede, inu rirun nigba kugba ara wiwo, Ẹsanri ehin didun sisa ati aiko riran kedere ko dara buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa dida ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile meje abo (7/6) pere Igo kekere ṣile mẹrin abo (4/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Arun ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

# YẸYẸNATU

## ONIYẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu:- Olotu, e ma ku eti igbo
Olotu:- Ewo le gbọ?
Yẹyẹnatu: Nwọn ni baba ti mọ adirẹsi Jesu nisisiyi.
Olotu: Baba wo?
Yẹyẹnatu:- Baba to ni Jesu ko ni adirẹsi lọjọ
Olotu:- Se iwọ na mọ ọdọ Jesu?
Yẹyẹnatu:- Ẹ bi Akintọla kẹ Tabi on kọ lo korin pe 'Bo ba ṣe pe mo mọdọ Jesu.
Olotu:- O ti korin bee?
Yẹyẹnatu:- O ni on iba lọ bebẹ adura:
Olotu:- Yẹyẹnatu, ṣe nkan ti o nsọ da ọ loju nitori orukọ Oloye ni o nda yi, ofin le mu ọ o.
Yẹyẹnatu:- Ti bi Roy Chicago na ti di Oloye? Sorry o, ko sa tile pe.
Olotu:- Bawo?
Yẹyẹnatu: Ṣe bi enia ba je Ijebu ti nwọn ko fi oye ni Ijebu, o le jo e ni Ondo kẹ.
Olotu:- Yẹs, aye ni ayo ije kẹ
Yẹyẹnatu:- Bi enia ba si jẹ agba ijọ ni o le jẹ Iadani ni mọṣa—lasi.
Olotu: Nitori kini?
Yẹyẹnatu: Nitori tibi na ni.
Olotu:- Ewo ni tibi.
Yẹyẹnatu: Nitori ọgbọn apo owo
Olotu:- Tabi iye ti nwọn nsan fun awọn Oloye ni yẹn?
Yẹyẹnatu: Iyẹn Oloye ti o ba le maa wọ aṣọ obinrin kiri loru.
Olotu:- Ha! Yẹyẹnatu, iwọ ri iru iyẹn ri ni
Yẹyẹnatu; Yẹs kẹ.
Olotu: Lọ ọ wo?
Yẹyẹnatu: Ng o kuku ṣọ.
Olotu: Hẹ wi ki a gbọ.
Yẹyẹnatu: Ṣe mo wi fun yin pe ọrẹ yin ni oun fẹ ri mi
Olotu; Ọrẹ mi wo?
Yẹyẹnatu: Ọrẹ yin ti o wa ni Ibadan nisisiyi
Olotu: Mo ti wi fun ọ ki iṣẹ ọrẹ mi.
Yẹyẹnatu: O ti da be niyen Ṣe bi enyin ni e e mu emi mọ ọ.
Olotu: O dara kini o ṣe?
Yẹyẹnatu: Lo ba di ale ọjọ kan ni derebi kan gbe moto duro niwaju ile wa lo ba wọle
Olotu. Pe kini?
Yẹyẹnatu: O ni iya Abayomi nbere mi ninu moto
Olotu: Iya Abayọmi ke
Yẹyẹnatu: Aburo Suberu ni mo tile pe e, ni mo ba be sita Bi mo ti yọju sinu moto ọrẹ yin ni mo ri ninu up-and-down?
aya ;oya to ni ki nma sọrọ o
Olotu: Ha ha ha Yẹyẹnatu onirọ
Yẹyẹnatu: Ẹ ie bere lowo re ke
Olotu; O dara kini o wa ṣẹlẹ.
Yẹyẹnatu: O ni ki npade on ni Ikeja,
Olotu: Irọ ni o npa.
Yẹyẹnatu: Ṣebi ọjọ na ni kọntira li fi yen bọ si fun Suberu.
Olotu: Ha Yẹyẹnatu, aṣe nitori kọntiralẹt ọkọ re lo ṣe ntẹle wọn.
Yẹyẹnatu: Irọ ni yẹn odabọ.

### LATI OJU EWE KEJI

Irohin na si tun se afikun wipe bi yi ni awon yio ma ra oja na gẹgẹbi adehun ti awon Ijọba mejeji ti ṣe ni arin ara won ninu odun ti mbo yi Ijọba Yugosl via yio ra ju oja ti o ra ni Naijiria ninu odun yi ju ti odun ti nbo yi lo.

# EGBOGI JẸDIJẸDI

### BERE FUN EGBOGI "CYCLEVEN"

Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara lati ṣe iwosan rẹ patapata

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri odẹ nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la le r mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradaria Awọn ẹlomiran lere wipeboya bi awọn ba lọ si n Dokita lati lo ke eyiti o ba uyo jade lati omusu ku il pa bẹ awon o bo lowo rẹ patapata

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun aiẹ Iyonu rà jo si tun ma bẹrẹ bakanna, Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa keini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbonse dede tabi lojojumọ, elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke yiogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa ije Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedijedi orişirişi n o wa e wo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu oluso ta i ti o ba nmu wa lẹhin igbonsẹ tabi ba nyo ti o bi ṣe lgbotsẹ tan ni, tabi ti nrin o ninu musu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon ynbo Jamani fere wa id rẹ ko ki o si dawo o işi mẹal yio daju wipe iwo yio bo lowo Jedi patapatarslaoau tio de s i ekeji re ko si ninu gbogo begbogi or

yi Nsina Here re ni:—
WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm ChurchStreet Phone 22787
LAGOS Nigeria, (Ọja Ito Faji

## IWE KOṢEMANI NI EYI

### IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO

NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ

"KOṢEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Leti Ọja Jankara)

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

# NIPA DYNAMIREN TỌNIK

ALE-BI-ALE Egbogi To I iamonu, tilu ti gbogbo a Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Ira agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan I san tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣefun daradara ti Emi Breath nu ko ba kuile daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi nu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ube lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di tun pafapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o g hunjọ yio bi yabo dada tiAra rẹ yio gbe kankan ni agba yio sao pẹlu ioq m udeu brode o iyẹn da baş



Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos P. O Box 333

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos
ATI NI ṢỌBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

## Angelina Super -- Rose

(O TI LỌ WA JU)

Eleyi sẹşẹ jade ni ko si nita rara Aşẹşẹ jade akan ako mọ ibiti o nlọ Ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lomọde lagba ọkunrin ati lobinrin O tun wa fun irun didi ati kiko elono o nmu irun ọkunrin papa ma dan ki o si jọlọ O ma nra ni ẹwa akotun awọ ara yio si yọ jade perepere.

Bi enia dudu ba loo yio ma da gẹgẹbi jigi Enia pupa kuku ti wa tẹlẹ.

Oere sare watabi ki o kowe fun tirẹ leni ki o to tan n lest Afcan Cosmetic Industries" 35' Ọmọwunmi S Tno District Council Mush o ẹtọju ara ati irun nyin ẹt Wew pọku ni 1/3d fun ẹyọ kan 15/- fun mejila

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,597 WEDNESDAY DECEMBER 29, 1965 (2D)


## Egbe Odo Afẹnifẹre Fẹ Ki Balewa Fi ipo Rẹ ilẹ

IFỌN:— Awon ọmọ egbe Ọdọ Afenifere ti Ifọn Ieba ilu Ọwọ ti kesi Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Apapọ Ijọba ilẹ Naijiria pe, ki o tete fi ipo re sile kiakia nitoripe ohun ti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti si nda aguntan si koba oju mu rara ati wipe iwa ti o nhu nipa Ipinlẹ na fi han pe, Ọlọla Balewa ko to ilẹ Naijiria toju mọ.

Gẹgẹbi eda iwe ti awọn ọmọ ẹgbẹ na fi sowọ si wa ni nwọn sope awọn lodi si ọrọ ti Alhaji Balewa so ni ilu Oyinbo nwọn ni tani ran nise lati lọ ba Oba'binrin ilu ẹkọ Oyinbo ninu ọrọ nwọn ni a tun ka ninu iwe na pe nigbati ilẹ Naijiria ko toro beni ko gun kaka ki o mojuto awọn ibiti o baje ninu ilẹ Naijiria ilẹ Rhodesia ti ko kan lọwọ kan lẹse ni o wa nmojuto

Nwọn ri Ipinlẹ Iwọ Orun ti ri ni asiko yi ko dara to rara kakaki ọlọla Balewa wa ọna ti edeaiyede to wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun yio se dara ti ija idara sun enia ile ati moto yio fi depin ilẹ Rhodesia ti won ko pa arawon ti alafia wa nibẹ ni Alhaji Balewa nitori rẹ fo lọ si ilu Oyinbo si.

Ni ipari ọrọ nwọn ni owon wa kesi ọlọla Balewa ki o sọ fun araaiye gbọ lori ipo ti ọgbeni Esua fi sile nwọn ni o yẹ ki o mọ idi pataki ti o fi fi ipo aye alaga igbimọ idibo sile.

# OLOYE OKOTiE-EBOH FẸ FI IṢẸ IṢELU SILẸ ?

**WARRI:—** Gbogbo enia to wa nibi ayẹyẹ eyẹ ifi ọba titun ti ilu Warri ọba Atalyeluwa Olu ti ilu Warri jẹ Ọba titun fun la iala lo ya ẹnu silẹ ti nwọn ko le pade ni gbati Oloye Festus Okotie-Eboh minista Alamojuto eto Iṣura fun apapọ Ijọba Naijiria ati Atapo egbẹ Alakuko nsọ fun awọn ọkẹaimoye enia to wa sibi ayẹyẹ na pe oun ko ni pẹ kuro ninu eto ọrọ iṣelu bayi.

Oloye Okotie-Eboh tun se alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe, gẹgẹbi gbogbo awọn enia ti mọ tẹlẹ pe o ti pẹ diẹ ni asiko ti oun ti ngbero lati jawo kuro ninu eto ọrọ iṣelu lati le simi fun ara on.

O tun ṣe alaye pe ohun ti o fa to mu ki on tun wa ninu eto ọrọ iṣelu eyiti on si wa ninu eto akoso ninu Ijọba apapọ ilẹ Naijiria ati pe o ti wu on lati lọ tete ti opin si ọrọ eto iṣelu lati le simi fun asiko ti o ku fun on lati lo.

Minista na tun ṣe alaye pe o ti to asiko bayi lati ṣe eto iyipada lati igbati nwọn ti ni edeaiyede kan ni ilẹ kiri Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria ati pe ki nwọn wa enia ti nwọn yio mu pada si ara aye ti o fa edeaiyede ni ilẹ na ti yio tẹ awọn enia lọrun.

Oloye Okotie-Eboh tun dupẹ gidigidi fun aye ti awọn fun on lati le ṣe eto eyiti yio mu ilosiwaju wa fun awọn enia ilẹ on ati paapa julọ fun Orilẹ ede Naijiria. O tun ṣe alaye pe ohun ti on ni igbagbọ si ni pe ko si enikẹni ti yoo to jẹ wipe on ko yio ma so agbẹ ilusọ fun awọn enia titi lai,

Oloye Okotie-Eboh tun se alaye pe ohun ti gbogbo enia ni lati mọ daju ni pe enia ti o jẹ wipe o wu lo fun gbogbo orilẹ ede ni lati ri mọ pe on ni isinmi fun igbakan fun Orilẹ ede eyiti o jẹ wipe o wulo fun lati igba diẹ wa ati pe iru enia bẹ yio jẹ eniti nwọn yio si ma ṣe iranti rẹ ati pe ki nwọn si ni igbẹkẹle ninu rẹ.



OLOYE OKOTIE EBOH Minista Alamojuto eto isura fun apapọ Ijọba Naijiria

Minista na tun se alaye pe lẹhin ti on ba fi eto ọrọ iṣelu silẹ o ni o da on loju pe awọn enia Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria yio tun ri ninu ọmọ Ipinlẹ na ti o jẹ pataki ti yio tun wa ninu eto akoso Ijọba apapọ Naijiria ti yio jẹ Aṣoju fun Ipinlẹ wọn.

O tun ṣe alaye pe iru enia ti yio jẹ Asoju fun ilẹ Itsekiri ati paapa julọ Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun yio si jẹ enia kan ti o tọ ti o si yẹ eyiti ko si le doju ti ilẹ wọn ati Ipinlẹ na pẹlu

Oloye Festus Okotie-Eboh tun kesi oba titun na lati huwa gẹgẹbi ọba Solomọ ni ti igba laelae lati ni ibẹru Ọlọrun lọkan ati pe ki o si ni ọgbọn ati oye eyiti yio fi ma ṣe eto akoso awọn enia rẹ ti nwọn yio si gbọ ọrọ si ara won lẹnu ti ki yio si ede aiyede larin ara won.

O tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ pe ohun ti o jẹ wipe o se pataki nipa isọkọpọ ti o le ni, ki yio jẹ wipe lati ọwọ Ọlọrun ni yio ti wa ti yio tun fun ni Ọgbọn ati Oye eyiti yio fi le ṣe eto akoso awọn enia Itsekiri ninu asiko ti o jẹ wipe nwọn wa ninu soro bayi ti gbogbo nkan yio lọ ni eto ọna rere

Ninu ipari ọrọ rẹ Oloye Okotie Eboh tun kesi ọba na lati ri daju daju pe on ṣura gidigidi nipa eto oro iṣelu ki o si ri i pẹlu pe on ko si fi are mo ẹgbẹ oṣelu kankan bikoṣe wipe ki o ri daju pe on ni isọwọpọ pẹlu Oloye Dennis Osadebay ti iṣe Alakoso Ijoba Ipinlẹ Agbedemeji Iwo Orun

O tun rọ Oba na lati ri pe on ni isọkọpọ pẹlu Ijọba Ipinlẹ rẹ ati pe ki o si se iṣẹ rẹ lọna to tọ ati eyiti o yẹ ki o mase se oju saju kankan larin awọn enia rẹ ati pe ki o ri daju pe awọn enia ilẹ on si ni ajumọsepọ pẹlu awọn ẹlẹgbẹ wọn ni jakejado pinlẹ na ati paapa julọ ni Orilẹ ede Naijiria Oloye na tun rọ Ọba na pe ki o mase nkankan koja Ọlọrun biko se pe ki o ni ibẹru Ọlọrun lọkan ati si ẹnikeji rẹ pẹlu.


## Asalam Alaikum Jammah !

**Nafila Oru Oṣu Ramadan.**

Lati Ọwọ ALUFA AKEWULA

ORU OJỌ KEJE 29/12/65 :— Irun mefa. Salamọ meta lori iduro Irun kookan, ọo ke:-Fatiha kan; Kulya ayuol-kafiruna meje ati Kul-hua-Allahum meje.

KA IROHIN—IMOLẸ FUN NAFILA TI ỌLA



Printed & Published By Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 29/12/65